# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

NO 861 WEDNESDAY DECEMBER 2 1964 (2D

## Ogunsanya Ni Nwọn Yio Dibo Fun Iha Gusu Ikẹja

IBADAN:— Gẹgẹb rohin kan t o de ọwọ wa ... egbe Alakukọ ni ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria, ti irohin na ti de ọwọ wa pe Oloye Adewtan Ogunsanya ti o jẹ ọmọ ile igbimọ asofin ti apapọ ... lati ... yio tuka laipe yi ati Alaga Igbimọ ti ndari iṣẹ ẹgbẹ Alakukọ ti ilu Eko ... pe nwọn yio dibo fun gẹgẹbi ọmọ ẹgbẹ Ilọsiwaju Naijiria UPGA ni iha Gusu Ikẹja.

Irohin lati ọwọ awọn Igbimọ ti ndari iṣẹ ẹgbẹ Alakukọ ni ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria na tun fi ye wa pe awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ meji ni nwọn yio dibo fun lorukọ ẹgbẹ Ilọsiwaju Naijiria UPGA eyiti ẹgbẹ Afenifere yio yan enia kan silẹ lorukọ ẹgbẹ Ilọsiwaju ilẹ Naijiria, sugbọn awọn ko fi daruko awọn ọmọ ẹgbẹ UPGA meji na ... Igbimọ ti ndari iṣẹ ẹgbẹ Alakukọ ni Ipinlẹ Iwọ Orun ... alaye pe ko si ọrọ kankan lori pe nwọn fẹ ... Dokita Mac. Jaja gẹgẹbi eni ti yio wa ni aye ijoko ati pe Dokita Mac Jaja ko fi igbakan ko iwe fun aye ijoko na rara.

# ROGBODIYAN NLA SẸLẸ LARIN ẸGBẸ NNA

## Awọn Olori Ẹgbẹ Pe Ipade Pajawiri

**EKO:– Ni ọjọ Aje ti iṣe ọgbọ jọ oṣu to kọja ni irohin kan de ọwọ wa pe awọn ọmọ ẹgbẹ "Nigerian National Alliance" (NNA) eyi ti ise ajumọsepo ẹgbẹ Dẹmọ (N N D P) MDF ẹgbẹ Olomi NPC ati NDC nba ara wọn ja lori eto gẹgẹbi nwọn yio se pin aye ijoko laṣiko idibo si ile igbimọ asofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria to mbọ yi**

Irohin na si tun fi ye wa pe awọn Olori ẹgbẹ NNA ni ipinlẹ Gusu ilẹ Naijiria si ṣe ipade kan ni ile Olori ẹgbẹ na ti ipinlẹ Ariwa Naijiria eyi ti awọn Olori ẹgbẹ na ṣe ni ilu Eko ni ọjọ Aje ti iṣe ọgbọnjọ osu to kọja lati le se eto gegẹbi ija nla to wa larin awọn ọmọ egbẹ na lori ẹni to tọ ati eyi to yẹ lati mu silẹ gegẹbi ọmọ ẹgbẹ ti yio gbe apoti ibo silẹ lorukọ ẹgbẹ NNA.

Oniwe irohin wa tun se alaye ninu irohin rẹ pe nibi to jẹ pe ija ti nlọ laini ipari bayi ni awọn ti ẹgbẹ ti a npe ni Niger Delta Cangres (NDC) ti o jẹ ọkan ninu ẹgbẹ to papọ di NNA lati ipinlẹ Ila Orun Naijiria.

Irohin na fi ye wa pe awọn ẹgbẹ ti a npe ni Niger Delta Congress NDC na ni a gbọ pe awọn ti pin si ọna meji bayi eyi to jẹ pe nwọn si nba ara ja lori eto ijoko ti nwọn yio ti mu enia silẹ lasiko idibo to mbọ yi Oniwe irohin wa tun sọ alaye ninu irohin rẹ pe awọn ẹgbẹ na to ti pin si ọna meji ni Ipinlẹ Ila Orun bayi ni irohin fi wa ye pe awọn ẹgbẹ na yio jijọ mu ọmọ ẹgbẹ kọọkan silẹ lati ba ara wọn jadu aye ijoko kanna.

Awọn ọmọ ẹgbẹ N.D.C. ti nwọn pin ara wọn sọna meji bayi ni Ọgbẹni Harold Briye si jẹ olori apa kan ninu ẹgbẹ na ti Ọgbẹni okilọ ti o jẹ Minista kekere ninu Ijọba Apapọ ilẹ Naijiria, oniwe irohin wa tun e alaye fun wa ninu irohin rẹ pe Ọgbẹni Harold Borive si lọ sibi ti nwọn ti ṣe eto ipade gẹgẹbi awọn olori ẹgbẹ na yio ṣe le pari ija nla to sẹlẹ larin awọn ọmọ ẹgbẹ wọn lori eto aye ijoko ati ẹni ti nwọn yio mu silẹ

Eyi to jẹ ohun iyalẹnu pupọ ju ninu ọrọ awọn ọmọ ẹgbẹ NDC ni apa kẹta ninu ẹgbẹ Niger Delta Congress NDC eyi ti awọn apa kẹta na ti binu kuro ninu ẹgbẹ NNA ti nwọn ti yara ronu wọn jinlẹ dada ti nwọn si ti pada sinu ẹgbẹ ilọsiwaju ilẹ Naijiria UPGA Awọn apa ẹgbẹ NDC eyi ti iṣe ọkan ninu ẹgbọ NNA ti nwọn pada lẹhin awọn ẹgbẹ na ni ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ na to pada ti ṣe alaye fun oniwe irohin wa



Alhaji Ahmadu Bello

pe eleyi ti fi han pe ẹgbẹ NDC ko le ri ijoko kankan ni Ipinlẹ Ila Orun Naijiria lasiko Idibo si ile Igbimọ asofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria to mbọ yi.

Oniwe Irohin wa tun fi ye wa pe ninu awọn ẹgbẹ NNA ti awọn tun wa ni Okitı-Pupa ni a ti gbọ pe awọn ẹgbẹ na ti pin si ọna orisirisi bayi lori ija to jẹ pe o nsẹlẹ larin awọn ọmọ ẹgbẹ na nigba gbogbo lori eto aye ijoko ati ẹni to jẹpe o yẹ ki awọn ọmọ ẹgbẹ na mu silẹ lati dibo fun lorukọ ẹgbẹ wọn lasiko Idibo to mbọ yi.

Ni ipinlẹ Agbedemeji Iwọ Orun Naijiria ni a ti tun gbọ pe awọn ẹgbẹ na nja lori aye ijoko eyi to jẹ pe Olori ẹgbẹ NDC nfẹ fi ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ wọn lati wa gẹgẹbi ọmọ ẹgbẹ wọn ti nwọn yio dibo fun lasiko Idibo to mbọ yi ni iha Iwọ Orun Ijaw Oniwe Irohin wa tun ṣe alaye pe ibẹ na gan an ni Olori ẹgbẹ „Mid West Democratic Front" M D F Ọgbẹni James Otobo tun nfẹ ki ọmọ ẹgbẹ wọn sibi aye ijoko ti Olori ẹgbẹ



Oloye Samuel Akintola

NDC nfẹ fi ọmọ ẹgbẹ ti wọn si. Ogbẹni James Otobo si wa ni ilu Eko lori eto gẹgẹbi nwọn yio ṣe pari ija nla to wa larin awọn ọmọ ẹgbẹ NNA

Ọgbẹni James Otobo tun sẹ alaye pe ibi to jẹ pe Olori ẹgbẹ NDC nja fun yan si jẹ adugbo awọn ọmọ ẹgbẹ tou ati pe ko si ọna fun ẹgbẹ NDC lati ma lọ jadu aye ijo ko na.

Ni ilu Pọta ni Irohin tun fi ye wa pe awọn Olori ẹgbẹ Dynamic Party ni ilu Pọta si lodi si pe ki apakan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ NDC eyi ti Ọgbeni Biriye si jẹ Olori wọn lati mu ọmọ ẹgbẹ silẹ ni agbegbe na Olori ẹgbẹ Dynamic Party na ṣe alaye pe Pọta si jẹ ibi kan ti ẹgbẹ Dynamic Party to ni agbara

Irohin tun fi ye wa pe ni iha Gusu ilu Aba ni ipinlẹ Ila Orun Naijiria ni a ti gbọ pe

WO OJU EWE KẸFA

UPGA Flag Now Ready

FLY UPGA FLAG FOR UNITY, PROGRESS, PROSPERITY & STABILITY
OBTAINABLE AT UPGA BUREAU OF PUBLICITY & INFORMATION
2 NNMADI AZIKIWE STREET, LAGOS
PHONE: 24381 & 22637
PRICES: CAR SIZE 6/- LARGE SIZE 35/-
LIMITED QUANTITY AVAILABLE

# Awolọwọ Dorişa (Apa 6)

Bayi ni ọrọ mi nipa Baba wa Cloye Awolọwọ ti şe lọ si. Iba şe bakanna ni ile Ibo ti ki ba şe pe awọn mo pe ẹgbẹ afẹnifẹre yio gbesan lara wọn ni 1 ẹ Yoruba.

## Lati Owọ Adio Mosanya



Oloye Obafẹmi Awolowo

Ninu iwe irohin ati ninu redio ẹgbẹ NCNC ati ẹgbẹ NPC bura pe awọn yio pa ẹgbẹ Afẹnifẹre bẹni ẹgbẹ Afẹnifẹre ko damọran pe awọn yio pa ẹgbẹ kan rẹ ri. Kaka bẹẹ, ohun ti ẹgbẹ na şe pẹlu gbogbo agbara ati eto rẹ ni lati le bori awọn ẹgbẹ yoku, ki işe lati pa wọn rẹ.

Itan yio jẹri niwaju awọn iran ti mbọ pe iwe ọrọ ti awọn aşofin ni ilu Eko nsọ ni ile igbimọ wọn fihan pe lati ọdun 1959 ni awọn kan ti nbere bayi: "Ko ha si ofin ti Ijọba apapọ ilẹ Naijiria le şe lati tu Ijọba ilẹ Iwọ Orun ka?" Nisisiyi, boya awọn ọmọ Herodia le ri "ori Johanu Onitẹbomi" ninu awo ọbẹ wipe. Şugbọn ki awọn enia ma pe ohun ti ko dara ko le dara lailai.

Ẹniti o ba gbin atẹgun yi ni yio ku. "Ati wọ ọmọ binrin Babiloni, ẹniti a o parun; ibukun ni fun ẹniti san fun ọ gẹgẹbi iwọ ti huwa si wa" Ọdalẹ, gẹgẹbi ida nyin ti sọ iya di alaili mọ bẹna ni niya ti yin yio di alaibomo larin obirin.

NJẸ O YẸ KINKAN WỌN MU ỌKANAWỌN OLUFỌKANSIN RẸWẸSI

Ni akota, ẹ jẹki a dupẹ lọwọ, gbogbo awọn ti o duro gboingbọin lẹhin ohin ti nwọn gba si otitọ lai bẹru ọta, ikorira ati iku pẹlu. Ẹ jẹki nẹ ran nyin leti pe ni okun Hastings ni Ọba Wileme, Aşẹgun ti şubu lori ẹşin rẹ, Inu awọn ọta re dun, nwọn si ro pe ogun ti ropa. Awọn ọmọ ogun fẹrẹ ba ọkan jẹ nitoripe nwọn ro pe o ti ku. Şugbọn lojiji, Wiiẹnu Aşẹgun dide o si fo s' oke. O si kigbe "Mo wa laye. mo wa laye Lagbara Oluwa, ngo şe ogun yi loni" ẹniti o si şẹgun, Bẹna ni yio si ri fun Awolọwọ. Lagbara Oluwa, Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ yio şugun ija ọşelu yi. Ki şe ibọn ati ake l' a o ko le ko ọmọ ogun ọta lọ bi awọn ebi mi, awọn ọmọ ni ati ile mi ja. Kaka bẹẹ, ngo jiya pẹlu awọn enia mi.

AFATỌ

Kini iba mu ki awọn nfẹ dide lati fa işubu awọn enia wọn? Afatọ ni. Afatọ ko mọ eida niwọn igbati o ba le pe ibiti o nfẹ. Fyi ni o nmu ki awọn ẹlomiran gba be ara wọn nitori ipo ti nwọn ndu. Gbe iru enia hẹ si ipo adele, nwọn yio bẹrẹ si gb' ogun ti iyekan wọn. Ki nwọn ba le gba ipo eniti nwọn de'ile fun, ara wọn a ya gaga lati wo ile baba wọn pẹlu. Gẹgẹbi ara Spata, nwọn ko bikita lati fi aşiri ọna Tamopile han ọta.

Nwọn a pinu bi arakunrin Titu Otis. Işẹ eru ni nwọn njẹ fun ọga wọn. Nwọn a di ẹni buburu lati ronupiwada, o ya wọn lara lati lọ si orun ẹgbẹ pẹlu ese wọn gẹgẹbi ọrẹ. Nwọn ti gbagbe pe ẹnitan ni o gbe wọn de ipo ọla ati "Ohun ti a şe fun alaimọre s'ẹgbẹ."

IRU AŞIWAJU WO NI YORUBA FẸ

Bi aşaju ba ti mo bẹni ola ati agbara orilẹ rẹ yio mọ. Iru Aşiwaju wo ni Yoruba nfẹ? Ngo daba idahun si Ibere yi. A fẹ aşiwaju ti awọn aşiwju awọn ẹya miran ko le f'ọwọ rọ sẹhin ninu ọgbọn lakaye, ati pẹlu ni igberaga. Ẹya Yoruba, gẹgẹbi awọn ẹya yoku, ni Ijọba tirẹ ti o yẹki a bu ọla fun şugbọn ki ee pe a ko fẹ irẹpọ ilẹ Naijiria.

Ayanmu ni o ti mu Yoruba Hausa ati Ibo ko ara wọn. Awọn Yoruba ko le ya kuro nisisiyi, idi rẹ ni yi ti o jẹ pe Yoruba ni o şe wahala ju awọn ẹya meji yoku lọ lati ri pe irẹpọ wa larin gbogbo wọn. Pẹlu bẹre bayi pe "Bawo ni eni meji şe le rin pọ lai jẹ pe inu wọn ko inu?" Lori kini a wa fi adehun si nigba;i Sardauna bẹrẹ si fọn ẹnu ba. "Ng ko de ri oko babam ko parẹ" O tun sọ bayi pe:

Ngo gb' ozun ti sa lẹ Odo Nya ngo şi pin ile ile na larin awọn mejeji gẹgẹbi bi ba a nla wa tiẹe ni ile a tirẹ. Nwọn nigbati igbakeji re le ya no so bayi pe. "Ara oke odo Oya ni mi ki to di ọmọ Naijiria

BI ARA RẸ SILẸ PATAPATA LỌWỌ IKỌ BUBURU GBOGBO NIPA LILO EGBOGI:—

RICHALET dajiriro. Işẹ rẹ lara k Kau fun Iwosan gbogo kokoro buburu t o bi

FUN ARUN ẸJẸ ninu, ẸJẸ ARA bi Mọnamọ-ARA EIA GBOGBO

Meji rẹ ko si ni gbogbo awọn Egbogi ti nwọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti nwọn si nta Kakiri ni owo pọọku adi ọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo Iyẹn şe ewẹ, a wa ki ta awọn egbo i ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npo ta ni ilẹ yi.

Gẹgẹbi awọn Onbiara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi ba wọn yẹn a ma a ba ojulowo egbogi atata ti a ranşẹ fun tita lati awọn ilu Jamani Faranse ati awọn Tatambulu si Itali jẹ.

Mọ daju pe, bi ẹjẹ arb ko ba mọ daradara awọn amodiagbe ailera wọnyi le şe ọ Lakulaku orişirişi Inaru, Oju şuşu tabi didun, Jẹdijẹdi Ako ibu arun Ẹdọki, Aya didun pupọ ati Ekur laya.

Ara riro, lapalapa, Egbo-ẹsẹ modi Apo ile itọ, ẹnin didun tabi ibaradi riro pẹlu Egbogi RISALETI a ma a gbogbo kokoro buruku ti o wa ninu ẹjẹ rẹ patapata yio si fọ ẹjẹ mọ to nitoni pẹlu.

Şa dan igo rẹ kan wo iwọ yio si ma a rohin rẹ fun ẹlomiran pẹlu. PRICE 13/6d postage 36/




WATERLOO MEDICINE STORES
Palm church Street, Lagos

# IWE SI OLOTU

## Ẹgbẹ UPGA Ni Okitipupa Nse.

Olotu Jọwọ gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin oloyin-i mọmọ lati fi ye awọn Okitipupa ati agbegbe re to wa ni ilẹ Okere lati fi ye wọn pe awa ọmọ ilu Okitipupa ko fi igba kan kuro ninu ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Alakukọ inu awa enia ilu na si dun pupọ lati ri pe ẹgbẹ mejeji na jijọ papọ.

Awa ọmọ ilu Okitipupa si tun ka saara si Oloye Olu Akinfosilẹ lori ise ribi-ribi to nse ninu ẹgbẹ UPGA Eleyi si ni lati fi ye Minista wa na pe awa si wa ni ẹhin rẹ nigba gbogbo ati pe asi ni igbẹkẹle ninu



Oloye Akinfosile

Oloye Olu Akinfosile. Ni ipari awa ọmọ ilu Okiti-Pupa ati agbegbe rẹ rọ awọn enia wa lati mọ daju pe awa ko se ẹgbẹ Demọ. Olotu ese pupọ fun aye ti e gba mi,

Emi ni
Johnson Adesina
Okiti Pupa

## Yoruba Ẹ Fi Imọ Se Ọkan

Olotu inu mi yio dun bi e ba le gba mi ni aye ranpe lati ba awọn enia mi karo ojire sọrọ ni pa ibo to mbọ yi e jẹki ẹgbẹ UPGA ninu isowọpọ wa ni a le bori ibo to mbọ yi e jẹ ki a fi oju inu wo Nigbati a ni ki a wa pelu awọn ibo dapọ lati le ṣegun awọn ọta wa njẹ o ye ki awọn Yoruba miran tun ma fi wa dagunla lai fẹ fi ara mọ ẹgbẹ mejeji yi ẹgbẹ Alakukọ. Nigbati ẹru dunu ti alaru ni ki a je ṣen pa kini ki ẹni to ọ ni ẹru wi ibo mura tun ati re wa ọwọ lati le dapọ mọ wa lati rin pe a bori awọn ọta wa Yo-ruba ipo wo ni e wa, nigba-ti Ibo fi Iranlọwọ rẹ han Yoruba n bo ni e wa. Yo-ruba e fi imọ sọ kan ni a o bori ibo to mbọ yi. Mo ran

ti ọrọ Baba mi agba so fun mi ni igba pipẹ pe "Eran oke yio wọ mi ati pe Ẹra-n oni yo go ke wa, eni ti o sọrọ yi ni Oloye Alhaji Busari ati Balogun ti ilu Eko ọrọ agba bi ko ṣẹ lowurọ aṣẹ ni aṣẹ Ẹyin ko ri awọn N.P.C ti a fi si ẹhin di ẹni i wọn gba iwaju lọwọ wa Oluwa yio koo wa yọ ninu ofin tipatipa. Olodumare yio yọ wa ninu Ijọba awọn N.P.C.
gba mi Ẹ̀ṣu ko onj; o

Emi ni
Ọmọba Alli Balogun
EKO

## Ibarapa Nfẹ Ile Iwosan Nla

Olotu: Inu mi yio dun bi e ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin oloyin-mọmọ ati kesi Minista Alamojuto eto ilera fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ati Olotu Ijọba Ipinle na pelu lati jọwọ ran ilu wa Ibarapa lọwọ gegebi ile iwosan nla yio se de ibe eyi to jẹ pe ko si enia kan ti yio ma ṣe wahala lati le ri Dokita to gboju lati le ṣe itọju wọn.

Ilu Ibarapa ko kere ni gbogbo ilu to wa ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ṣugbọn eleyi yio si dara bi Olotu Ijọba Ipinlẹ na ati Minista Alamojuto eto ilera lati ṣe bi ile iwosan na yio ṣe tete de ilu wa na. A nreti bayi o Modupẹ aye ti e gba mi Ajinde yio ma jẹ o

Emi ni
Abiọla Afọlabi
IBARAPA



Oloye S. L. Akintọla Olori Ẹgbẹ Demẹ ati Olotu Ipinlẹ Iwọ Orun


**Aiye Toto African Healng Home**

Bere ogun itsja Ti o daju Ti a ṣe ni Turari pẹlu lọfinda. Tete ra tirẹ ki o gbadun rẹ Irohin ko to Afojuba orisirisi aruu ati ilọsiwaju
Lẹnu iṣẹpẹlu Ajẹbina ogun awọn Agba lo wa lọdọ wa

Office
7. Tadeyọ Road
Mushin

S. ỌLATUNDE
Native Doctor
6, Tadeyọ Rd
Mushin



**Ipolowo Ọja Rẹ Ko T Yege**

*Nitoripe*

O KO TI POLOWO ỌJA RẸ
SINU
**IROHIN IMOLE**

T'ODUN KA FUN GBOGBO YORUBA

KỌWE IPOLOWO ỌJA RẸ SI
A DVRTISMENT MANAGER

**IROHIN IMỌLE**
16, Bamgbose Street Phone 21985



GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN AYỌ NIPA „DYNAMIREN" TONIK



A TLE-BI-ALE Egbogi tọniki Jamanu titun ti kbogbo ara ilu Eko ati ja-fejado Naijiria mọ daju un Akọ agbara ati Ajẹ-bidan iṣẹ rẹ lara Agbala-gba Ọkunrin gbogbo.

Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala la-la ṣiṣe ti o ko le jẹun daradara, tabi ki o male sun dada tabi gbogbo awọn iṣan ara emi ko ba ṣiṣẹ daradara (Breath) inu rẹ ko ba gunlẹ daradara fun iṣẹ tabi wa-hala ṣiṣe tabi fun awọn ailera gbogbo tabi ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja ọgbọn ọdun o si de adọrin tabi ube lọ. Mọ daju pe "DY-NAMIREN ni egbogi ti o nfẹ lati sọ'ara rẹ di ọtun pa tapata ara rẹ a si jọlọ, eran ara rẹ ti o ti hunjọ yio yi po pada patapata alafia ati gbadun yio de si ọ lyẹn bẹ.

Bere egbogi na ni Ṣọbu:

NIGERIAN MEDICENE STORES
4, Tinubu Square Lagos
Waterloo Medicine Stores,
8, Palm Church Street, (Ọja Ita Faji
Lagos, Nigeria.
ADEDUN CHEMIST
14 Wakeman Street Yaba

# Irinajo Mi Si Agbo-Ile Ifẹlodun (Apa1)

### Lati Ọwọ Ajẹgborodagba

Mo ki gbogbo ẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ lọkunrin ati lobinrin ẹ ku iṣẹ o, mo si tun ki gbogbo ẹnyin ọmọ Igbomina jakejado ilẹ Naijiria ati ni Oke-Okun paapa julọ ẹnyin ọmọ Ijọmu—Oro.



Aworan oke yi ni ti Oloye Fhillip Afọlayan Ajiboye Gbenle lẹhinti nwọn ti wọ ẹwu oye ati ilẹkẹ iyun fun tan ni ọjọ iwuye na.

Ki nto bẹrẹ si ma ba nipa irinajo mi si Agbo-ile Ifẹlodun ni adugbo Isaga nilu Surulere leti Eko, ngo kọkọ juba awọn iya mi Oṣoronga, olomi ni ile fi ẹjẹ wẹ, iba awọn agbalagba, iba ọmọde ba aiye akamọra, ki iba mi ṣẹ, nitori iba ki hunni, adaṣẹ lo hunni.

Gẹgẹbi irinajo mi na ti lọ niyi, ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi ni deede agogo mẹjọ owurọ ni mo bẹbera pẹlu iwe ipe enia sibi ẹyẹ lọwọ mi mo wọ bọọsi ni ita Tinubu o di Surulere nigbati a de Surulere abọ silẹ ni Lawson, mo gbe ra o di agbo ile IFẸLODUN ni nomber 25, Isaga Road, Surulere.

Ni deede agogo mẹjọ owurọ ni mo de ibẹ, gbara ti mo de bẹ emi pẹlu ẹrọ ayaworan mi lọwọ ati iwe penpe pẹlu kalamu lọwọ, bi mo ti wọ inu agbole na ni ọpọlọpọ ninu awọn ọmọ Ijọmu — Oro ti o mọ mi ti bẹrẹsi sa mi ni meje - mẹjọ pe Ajẹgborodagba, Ajẹgboro o tun de bẹ ni tirẹ ri. Ki nma fa ọrọ gun lọ titi nwọn mu mi lọ ri Ọgbẹni wa A. K. Karimu Ọlabamiji Gbenle ti O nṣe Oluṣeto ati alamojuto ẹyẹ iwuye ọjọ na.

Bi Ọgbẹni A, K. Karimu si ti ri mi ni o yọ mọ mi, ti o simu mi yi gbogbo inu ile ti nwọn ti fẹ ṣe ariya ọjọ na ka pẹlu awọn alaye nipa bi eto na yio ṣe lọ lẹhin eyi o mu mi lọ han Oloye ti wọn fẹ wuye fun ni ọjọ na. o si ṣe alaye nipa bi mo ti jẹ fun

Lẹhin na o wa mu mi lọ sinu agbala nla ti nwọn ti pese silẹ fun awọn alejo lati lo wọ si, Ninu agbala na. oriṣiriṣi nkan meremere ni a nfi ṣe agbala na ni ọṣọ pẹlu awọn aworan Olowo iyebiye ni ẹwọ ọtun agbala na, ero aworan ti nwọn npe ni Television (Tiv) wa, ni ẹgbẹ osi, ero akorin nlanla ti o bu bi ara wa, O ṣe alaye agbala pe o jẹ afin ti oloye na yio ti ma gba atẹgun bi o si ti ni ki njoko ni o ba lọ sidi ero na, ti o si ko awọn awo rẹkọdu si ori rẹ, ti ẹrọ na si nṣiṣẹ lọ, ti angbadun orin adadun lati inu ẹrọ na.

Gbogbo asiko ti nkan wọnyi lọ ọti ṣinapu meji ni o wa niwaju mi ti nwọn ni ki fi yọ ẹnu mi nu na ki eto ariya na to bẹrẹ.

Mo fẹ fi eleyi ran ẹnyin ọkawe mi leti pe, Irinajo mi yi jẹ irohin nipa eto iwuye ni ilu Ijọmu-Oro ati iwuye nipa Olori ẹbi Gbenle ti nwọn

Alagba wa Oloye Phillip Afọlayan Ajiboye Gbenle jẹ ati igbesi aiye Oloye na eyiti ẹ o ma ka lati oni yi lọ ninu iwe Irhin Imọlẹ ni ojojumọ tabi ni ẹmẹta larin ọsẹ

Mo ro pe eleyi yio jẹ ki ọpọlọpọ ninu nyin mọ ọna ti nwọn ngba joye tab iwuye ni Idile kọọkan ni ilẹ Yoruba

Nigbati o di deede agogo mẹwa owurọ ọjọ na nwọn sọ pe ki a bọ silẹ lati ori oke pẹtẹsi ti emi ati awọn alabaṣe ọjọ na ti de nwọn mu wa lọ si isalẹ nibi ti o tẹju ti a ti to awọn aga si nibiti nwọn ti fẹ ja ewe oye ati awọn ohun elo oye na fun Oloye wa.

Nigbati a sọkalẹ tan ti ẹsẹ gbogbo enia si ti pe ṣamuṣamu, ti o fi jẹ pe ẹlomiran ko ri aye joko mọ gbogbo ita ni o si kun ṣọ-ṣọ, Ni nwọn ba pin iwe pepe kan fun gbogbo enia eyiti nwọn ti ko bi awọn eto iwuye na yio ti ma lọ si pelu awọn Oludari to na.

Lẹhin ti gbogbo awọn alabaṣẹyẹ gba iwe yi tan ni Ọgbẹni Shittu Adeyẹmi fi adura bẹrẹ aṣẹyẹ ọjọ na.

Lẹhin adura yi ni Ọgbẹni Karimu Adeoti Olohun iyọ wa ṣe apejuwe alaga aṣe ọjọ na, o si pe Ọgbẹni James Adewuyi lati wa gẹgẹbi alaga ọjọ na.

Nigbati alaga bọ si aye rẹ, O sọ idi pataki nipa ohun ti o gbe gbogbo wa wa si, o ni awa lati wa ba baba, wa wuye oye Olori ẹbi Gbenle Ijọmu Oro ti a fi jẹ.

O ṣe alaye nipa iwa rere ti Alagba Philip Afọlayan Gbenle nhu ati nipa bi o ti dara to ki enia ma huwa rere si ọmọ ẹnikeji, paapa ki o ma wa awọn ẹbi rẹ, lọkunrin ati lobinrin lọmọde lagbalagba, ki o si tun ma na owo si ọna ti o tọ ati ti o yẹ.

Iyoku Di Ọtunla

## Diẹ-diẹ Ni Ọlọla Njo!



Aworan yi niti igbati Oloye Phillip Afọlayan Ajiboye Gbenle nfi ẹsẹ rajo pẹlu awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na, o ki ọwọ bọ apo lati yọ Kọrẹnsi fun onilu ọjọ na Diẹdiẹ ni Ọlọla njo. Olowo ki njo bahun ẹ sa ma milẹngbẹ, bi ti Eko.

Ẹ ku Ijo o, Oloye, Oye a mọ ori o.

# IROHIN IMOLE

*IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA*

No. 261 WEDNESDAY DECEMBER 2, 1964 [2D]


## Ọlọsa Kan Lọ Fi Ẹwọn Ọdun Meji Jura

ILESHA: Ni ọjọ Aje ti iṣe ọgbọnjọ oṣu to kọja ni Adajọ ile ẹjọ kekere ti ilu Ilesha Ọgbẹni Tunji Adeyẹmi ju ọkunrin ọlọsa kan ti o jẹ Agbowo ori fun Ijọba Ibilẹ ti Iha Ariwa Ilesha si ẹwọn ọdun meji ati oṣu mẹfa lori ẹsun pe o ji owo ori ti nwọn ri gba eyi ti iṣe ti Ijọba Ibilẹ Iha Ariwa Ilesha onirohin wa fi ye wa pe iye owo ti Ọgbẹni Fọlọrunsọ Oginni ji ninu owo Ijọba Ibilẹ na jẹ (£395. 15/)

Agbejọro fuu ile ẹjọ na fi ye Adajọ pe lnu ọjọ kọkanlelogbọn oṣu kejọ si ọjọ karun oṣu kẹwa Ọdun 1952 ni Ọdaran na gba owo na eyiti o jẹ owo ti nwọn ri gba ni ile ẹjọ lori pe ki awọn enia fi tan ra eyiti Agbejọro ile ẹjọ na sọ pe ọdaran na ko san owo fun Olutọju eto owo fun Ijọba Ibile iha Ariwa Ilesha

Ninu idajọ Adajọ ile ẹjọ na ni o ti ṣe alaye pe ẹsun pe awọn Oṣiṣẹ ile iṣe Ijọba si ti npọju ni ilẹ ẹjọ bayi ati pe on yio fi Fọlọrunshọ Oginni ṣe arikọgbọn fun awọn elomiran ati pe on ju Ọdaran na si ẹwọn Odun meji ati oṣu mẹfa ki o lẹ fi tanran ẹsun ole na.

## Okpara Sọ Pe:

# IJỌBA APAPỌ KO NI AGBARA MỌ

**Ninu irohin to de ọwọ wa lati ẹnu Olotu Ijọba ipinlẹ Ila Orun ati Olori ẹgbẹ Alakoso ni o ṣe alaye pe ohun to le mu idaduro wa ninu eto lati tu ile Igbimọ aṣofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria ka ni Ijọba apapo ilẹ Naijiria na ti di alailera patapata.**

Olotu Ijọba Ipinlẹ Ila Orun ati Olori ẹgbẹ Ala na nsọ eyi nibi ẹyẹ eto ipa de ipolowo Ibo eyi ti o ba awọn ọmọ ẹgbẹ ilọsiwajn ilẹ Naijiria UPGA ṣe ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kọkandinlọgbọn osu to kọja yi.

Dokita Michael Okpara tun ṣe alaye pe Ijọba apapọ ilẹ Naijiria ti ẹgbẹ Olomi NPC nṣe akoso re ti o si ṣe alaye pe nse ni o dabi Ijọba kan to ko ni ero kankan lori tabi nkan to jẹ pe o si ye kankan ti nwọn fi pilẹṣe rara. Dokita Okpara tuu ṣe alaye pe lori Ijọba wọn ii o jẹ alailero na lo mu ki o pe to bayi lati le tu ile igbimọ asofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria ka lati ọjọ yi.

Dokita Okpara tun ṣe alaye pe ile igbimọ aṣofin ti apapọ Ijọba ile Naijria ti to lati tu ka bayi ati pe orukọ awọn adibo ko ti ba ara mu lo fa eleyi ati pe nigbati nwọn ko ri orukọ awọn enia ninu ọdun to kọja eyi ti Dọkita Okpara tun ṣe alaye fun awọn enia na pe orukọ awọn enia ti nwọn ka nigbana ko ba ara mu rara.

Dọkita Michael Okpara tun ṣe alaye fun awọn enia to wa sibi ẹyẹ ipade ipolowo Ibo na pe on ko ni ero pe eto idibo si ile igbimọ asofin ti apapọ Ijọba ọdun yi le tọna ni ipinlẹ Iwo Orun ati ipinlẹ Ariwa ile Naijiria.

Dọkita Okpara tun ṣe alaye pe to ba jẹ iru iya ti awọn ẹgbẹ Olomi NPC nfi njẹ awọn enia ti ko ba ti ṣe ẹgbẹ wọn tabi pe ki nwọn ma ju wọn sewọn laini eto kan to fi idi mule tabi lori pe ki awọn elomiran fi ara ma gbọgbẹ o ni olori ẹgbẹ na Alhaji Ahmadu Bello ko le sọ pe on ṣe ileri pe eto idibo to mbọ yi yio tona eto ofin ti ile Naijiria rara ni ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria.



ALHAJI ABUBAKAR TAFAWA BALEWA.
Alakoso Ijọba Apapọ

Dokita Okpara tun fi ye awọn enia na pe itori iru iwa ti ẹgbẹ Olomi N.P.C. ma nhu bayi lo mu ki nwọn na ti sọ orukọ awọn ọmọ ẹgbẹ ilọsiwaju ilẹ Naijiria UPGA ti nwọn yio dibo fun lasiko idibo si ile igbimọ aṣofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria ati pe ti nwọn ba lo da orukọ tabi ki nwọn fi awọn ọmọ ẹgbẹ na han ni ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria yio mu ki awọn ọmọ ẹgbẹ Olomi N. P. C. lọ mu ju wọn s'ọgba ẹwọn laijẹ pe nwọn fi ẹsun kan to fi idi mulẹ fi kan wọn. Dokita Okpara si se alaye pe eleyi ko mu ki ẹgbẹ NNA bori ibo yi bi ko ṣe pe nwọn yio kuna ninu idibo ti mbọ yi.

Oloto Ijọba Ipinlẹ na tun fi ye awọn enia na pe egbẹ ilọsiwaju Naijiria UPGA ti ṣe eto lati le jẹki awọn enia ilẹ Naijiria le wa ni igbesi aiye rere ninu Ijọba ti ẹgbẹ UPGA yio se akoso rẹ. Dọkita Okpara si tun se alaye ni ipari ọrọ rẹ pe ẹgbẹ UPGA ti se tan lati gba awọn enia ilẹ Naijiria kuro lọwọ akoso Ijọba ẹgbẹ Olomi NPC ati awọn Alabasepọ wọn ti nwọn ko mọ Ọlọrun ati pe nwọn ko si niyi loju awọn enia ilẹ Naijiria



DOKITA M. I. OKPARA
Olori Ẹgbẹ Alakoso

## Rogbodiyan Bẹsilẹ Larin Ẹgbẹ NNA

Lati Oju Ewe Kini

awọn ọmọ ẹgbẹ NDC fẹ mu enia silẹ gẹgẹbi ọmọ ẹgbẹ wọn ti nwọn yio dibo

Irohin na tun fi ye wa pe ẹgbẹ kan ti nwọn pe ara wọn ni "Republican Party" eyi ti Dọkita Okezie jẹ olori wọn si lodi si aye ijoko ti awọn ọmọ ẹgbẹ DNC ti sọ pe awọn yio ti mu enia si ẹ ati pe Dọkita Okezie ti kilọ fun olori ẹgbẹ NDC lati jawo kuro lori ọrọ na

Irohin na tun fi ye wa pe awọn Olori ẹgbẹ NNA ti mura lati le tete ri pe nwọn pari ija to nṣẹlẹ larin awọn ọmọ egbe wọn ati pe ki eto ọrọ lori aye ijoko na le tete pari ṣugbọn a tun gbọ pe awọn ọmọ egbe NNA ti nṣe eto miran bayi lati lọ si Kaduna ni ipinle Ariwa ile Naijiria lati lọ ṣe eto gege bi ija na yio ṣe pari larin awọn ọmọ egbe na. Irohin fi ye wa pe Olori ẹgbẹ Olomi NPC ni yio ṣe Alaga eni ti yio pari ija na fun wọn.


Printed And Published by Mudupe Printing Press, 16 Bamgboṣe Street Lagos Phone 21895
Acting Editor: (Adele Olotu) 'BAYỌ TIAMIYU 26, Omididun Street Lagos (2/12/64)